# YORÙBÁ LANGUAGE JSS 2 FIRST TERM NOTE

## Àgbékalẹ̀ Iṣẹ Táàmù Kìn-ín-ní - First Term Scheme of work

1. ***Ọ̀sẹ̀ Kìn-ín-ní - Week 1: Ede: Silebù Ede Yoruba.***

Orisi ati Itumo Silebu, Àwọn ohun tó ṣe kókó nípa sílébù èdè Yorùbá. Ihun Silebu Ede Yoruba, Oro Eleyo ati Olopo Silebu.

2. ***Ọ̀sẹ̀ Kejì - Week 2: Ẹsin Ibile Yoruba.***

Pataki Esin Lawujo Yoruba, Igbagbo ati Ero Yoruba Nipa Olodumare, orúkọ Ọlọrun nínú ẹ̀yà mìíràn, Awon orisa Ile Yoruba.

3. ***Ọ̀sẹ̀ Kẹta - Week 3: Asayan Iwe Itan Aroso***

Iso-ni-soki Ohun ti iwe Dale Lori, Kika iwe itan Aroso Pelu Awon Akekoo, Àwọn ẹ̀dá ìtàn, Kókó ẹ̀kọ́ ti ìtàn kọ́ wa.

4. ***Ọ̀sẹ̀ kẹrin - Week 4: Onka Yoruba***

Kika 200 – 400, Òǹkaye àti òǹkapò, òǹkà owó náírà.

5. ***Ọ̀sẹ̀ karùn-ún - Week 5: Gbolohun Ede Yoruba ati Iro***

Oriki àti àpẹẹrẹ gbólóhùn, Oríṣi gbólóhùn, awẹ́ gbólóhùn èdè Yorùbá. Gbólóhùn àṣẹ, gbólóhùn ìbéèrè àti gbólóhùm ìyísódì.

6. ***Ọ̀sẹ̀ Kẹfà - Week 6: Ìró ohùn èdè Yorùbá.***

Oriki ati Orisi Iro Ohun, Àwọn ohun tó ṣe kókó nípa ìró ohùn, fífi àmì ohùn sí orí ọ̀rọ̀, àwọn ọ̀rọ̀ tí àmì ohùn yà sọ́tọ̀.

7. ***Ọ̀sẹ̀ Keje - Week 7: Asa Iranra-Eni-Lowo.***

Itumo Pelu Alaye Lori Asa Iranra-Eni-Lowo, Awon Ona Iranra-Eni-Lowo Laye Atijo, Iranra-Eni-Lowo Laye Ode Oni.

8. ***Ọ̀sẹ̀ Kẹjọ - Week 8: Akoko, Igba ati Oju Ojo.***

Onka Ojo ati Osu ni Ede Yoruba, Siso bi Oju Ojo Se ri, Siso Iye Agogo To Lu ni Ede Yoruba, Ìlò A.M. ní èdè Yorùbá.

9. ***Ọ̀sẹ̀ Kẹsàn-án - Week 9: Asa : Ounje Ile Yoruba***

Oriki Ounje ati Anfaani Ounje, Orisi Ounje ati Ire Oko, Isori Ounje, Ìtọ́jú oúnjẹ àjẹṣẹ́kù.

10. ***Ọ̀sẹ̀ Kẹwàá - Week 10: Aayan Ogbufo ati Itesiwaju Orisi Gbolohun.***

Oriki Aayan Ogbufo, Ìwúlò aáyan ògbufọ̀, Aayan Ogbufo Eleyo Oro

### Òsẹ̀ *Kìn-ín-ní – Week One*

### *SÍLÉBÙ* ÈDÈ YORÙBÁ

Sílébù ni ègé tí ó kéré jùlọ nínú ọ̀rọ̀ èyí tí a lè fi ohùn gbé jáde lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo.

Bí àpeere.

| Ọ̀rọ̀ | Ìpín sí Sílébù | Iye Sílébù |
|---|---|---|
| 1. Bàbá | bà-bá – father | Sílébù méjì |
| 2. Ìyàwó | ì-yà-wó – wife | Sílébù mẹ́ta |
| 3. Aláǹgbá | a-lá-ǹ-gbá – lizard | Sílébù mẹ́rin |
| 4. Olóòótọ́ | o-ló-ò-ó-tọ́ - A trust worthy person | Sílébù márùn-ún |

| | | |
|---|---|---|
| 5. Ìjàngbọ̀n | ì-jàn-gbọ̀n – trouble | Sílébù mẹ́ta |
| 6. Ọmọlanke | ọ-mọ-la-n-ke – wheel barrow | Sílébù márùn-ún |

**Àwọn Ohun To Ṣe Kókó Nípa Sílébù**

1. Kọ́ńsónáńtì kò lè parí sílébù èdè Yorùbá.
2. Fáwẹ́lì méjì kò lè wà nínú sílébù kan.
3. Kọ́ńsónáńtì kò lè dá dúró gẹ́gẹ́ bí sílébù àyàfi kọ́ńsónáńtì aránmú aṣesílébù **"m" ati "n"**
4. Iye amì ohùn tí ọ̀rọ̀ kan bá ní ni iye sílébù tí ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ní. Sílébù kan à mì ohùn kan, sílébù méjì àmì ohùn méjì (abbl).
   Bí àpẹẹrẹ: Ọ̀kánlàwọ́n – Ọ̀-kán-là-wọ́n. Àmì ohùn mẹ́rin , sílébù mẹ́rin.

**Iṣẹ́ Ṣíṣe – Exercise 1.0**

Pín àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sí sílébù kí o sì sọ iye sílébù tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọ́n jẹ́. Break the following words into syllable and write the number of syllables in each word.

| | **Ọ̀rọ̀** | **Ìpín sí Sílébù** | **Iye Sílébù** |
|---|---|---|---|
| 1. | Àgádágodo | | |
| 2. | Àtẹ́lẹwọ́ | | |
| 3. | Àtàǹpàkò | | |
| 4. | Kòṣeémánìí | | |
| 5. | Ọ̀kánjúwà | | |

**ÌHUN SÍLÉBÙ ÈDÈ YORÙBÁ**

Ìhun mẹ́ta ni sílébù èdè Yorùbá ní

1. Ògédé fáwẹ́lì (f)
2. Àpapọ̀ kọ́ńsónáńtì àti fáwẹ́lì (kf)
3. Kọ́ńsónáńtì aránmú aṣesílébù (N)

1. Ògédé Fáwẹ́lì –Ordinary vowel (F)
   a. À – kà – rà (F-KF-KF)
   b. Ọ-ṣẹ (F-KF)
   c. I-lé (F-KF)

**2.** Àpapọ̀ kọ́ńsónáńtì àti fáwẹ́lì (KF)
   a. Kọ́-lá-dé (KF-KF-KF)
   b. gbà-ge-de (KF-KF-KF)
   **c.** jà-gù-dà (KF-KF-KF)

**3.** Kọ́ńsónáńtì aránmú aṣesílébù (N)
   a. Kọ̀-ǹ-kọ̀ (KF-N-KF)
   b. a-lá-ǹ-gbá (F-KF-N-KF)
   c. ọ-mọ-la-n-ke (F-KF-KF-N-KF)
   d. kẹ̀-lẹ̀-ǹ-bẹ̀ (FK-FK-N-FK)

**iṣẹ́ Ṣíṣe. Exercise 1.1**

kọ ìhun sílébù àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀. (Write down the syllable structure of the following words)

| Ọ̀rọ̀ | Ìpín sí sílébù | Ìhun sílébù |
|---|---|---|
| 1. àkàlàmàgbò | | |
| 2. Ọdẹ́kanlé | | |
| 3. Bántálẹ́ | | |
| 4. Èèrà | | |
| 5. Ìyálódeàríyá | | |

**Ọ̀rọ̀ Ẹlẹ́yọ Sílébù àti Ọ̀rọ̀ Ọlọ́pọ̀ Sílébù**

1. Ọ̀rọ̀ Ẹlẹ́yọ Sílébù (mono syllabic word): Èyí ni ọ̀rọ̀ tí ó ní sílébù kan.
   a. Wá – come
   b. Lọ – go
   c. Sùn – sleep
   d. Kà – read
   e. Kọ – write
2. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́pọ̀ Sílébù (poly syllabic word): Èyí ni ọ̀rọ̀ tí ó ní sílébù méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àpẹẹrẹ:
   a. Adé – A-dé
   b. Ajá – a-já
   c. Òkúta – ò-kú-ta
   d. Ìlẹ̀kùn – ì-lẹ̀-kùn
   e. Àgádágodo – à-gá-dá-go-do
   f. Gbòǹgbò – gbò-ǹ-gbò

**Iṣẹ́ Àṣetiléwà (Assignment 1.0)**

Pín àwọn ọ̀rọ̀ wọ́nyí sí sílébù, sọ ìhun sílébù wọn, sọ iye sílébù tí wọ́n ní kí o sì sọ bóyá ọ̀rọ̀ ẹlẹ́yọ sílébù ni tàbí ọlọ́pọ̀ sílébù.

| Ọ̀rọ̀ | Ìpín sí sílébù | Ìhun sílébù | Iye sílébù | Ẹyọ / ọ̀pọ̀ sílébù |
|---|---|---|---|---|
| 1. Adékúnlé | a-dé-kún-lé | F-KF-KF-KF | Sílébù mẹ́rin | Ọ̀rọ̀ ọlọ́pọ̀ sílébù |
| 2. Ìjàpá | | | | |
| 3. wá | | | | |
| 4. ṣọ́ọ̀sì | | | | |
| 5. òróǹbó | | | | |
| 6. igunpá | | | | |

**Iṣẹ́ Àṣetiléwá (Assignment 1.1)**

Parí àtẹ ìsàlẹ̀ yìí (Complete the following table)

| Ọ̀rọ̀ | Ìpín sí sílébù | Ìhun sílébù | Iye sílébù | Ẹyọ / ọ̀pọ̀ sílébù |
|---|---|---|---|---|
| 1. Òjògẹ́ | | F-KF-KF | | Ọlọ́pọ̀ sílébù |
| 2. Àkànjí | À-kà-jí | | Sílébù mẹ́ta | |
| 3. Panla | | KF-N-KF | | Ọlọ́pọ̀ sílébù |
| 4. Aláṕǹlá | | F-KF-KF-N-KF | Sílébù márùn-ún | |
| 5. Akiribọ́tọ́ | a-ki-ri-bọ́-tọ́ | | | Ọlọ́pọ̀ sílébù |

## ỌSẸ̀ KEJÌ WEEK 2
## ÌRÓ OHÙN ÈDÈ YORÙBÁ

Ìró ohùn ni gbígbé ohùn sókè àti sódò tí ó máa ń wáyé nínú èdè Yorùbá nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀.

**Àwọn Ohun tí ó ṣe Kókó nípa Ìró Ohùn**

1. Orí fáwẹ́lì àti Kọ́ńsónáńtì aránmú aṣesílébù ni a máa ń fi àmì ohùn sí.
2. A kìí fi àmì ohùn sí orí kọ́ńsónáńtì àyàfi kọ́ńsónáńtì aránmú aṣesílébù.
3. Àmì ohùn òkè kìí bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ ní èdè Yorùbá àyàfi ọ̀rọ̀ àyálò.
4. A kìí fi amìn ohùn ààrin sí orí ọ̀rọ̀.
5. Iye sílébù tí ọ̀rọ̀ kan bá ní ni iye àmì ohùn tí ó wà ní orí ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀.
6. Fáwẹ́lì "U" kìí bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ ní èdè Yorùbá àyàfi ẹ̀ka èdè.

**Oríṣi Àmì ohùn: Àmì ohùn mẹ́ta ni ó wà nínú èdè Yorùbá.**

1. Àmì ohùn òkè (m)( /)
2. Àmì ohùn ààrin (r) (-)
3. Àmì ohùn ìsàlẹ̀ (d) ( \)

**Fífi Àmí Ohùn Sí Orí Ọ̀rọ̀**

1. **Àmì Ohùn Òkè (m)**
   a. m – wá (come)
   b. mm –ṣíbí (spoon)
   c. mmm; Jíbọ́lá {a name}
   d. mmmm – pátápátá (everything)
   e. mm – pátá (pant)
2. **Àmì ohùn Ààrin. (r)**
   a. r – jẹ – (to eat)
   b. rr – ata (pepper)
   c. rrr – ọmọge (a beautiful girl)
   **d.** rrrr – ọlọ ata (grinding stone)
3. **Àmì Ohùn Ìsàlẹ̀ (d)**
   a. d – rà (buy)
   b. dd – ẹ̀pà (groundnut)
   c. ddd – ọ̀gẹ̀dẹ̀ (banana)
4. **Àpapọ̀ Àmì ohùn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta**
   a. rd – iyọ̀ (salt)
   b. ddm – ìyàwó (wife)
   c. dmr – òkúta (stone)
   d. rrm – ọmọdé (child)
5. **Àwọn Ọ̀rọ̀ tí Àmì Ohùn yà sọ́tọ̀**
   a. rm - owó (money)
      dd - òwò (business)
      dr - òwo (horn)
   b. rm - ọwọ́ (hand)
      dd - ọ̀wọ̀ (respect)
      rd - ọwọ̀ (broom)
      dr - ọ̀wọ (dew)
   c. rm - ọkọ́ (hoe)
      dd - ọ̀kọ̀ (sword)
      rr - ọkọ (husband)
      rd - ọkọ̀ (vehicle)
   d. rm – igbá (calabash)
      dd – ìgbà (time)
      rr – igba (200)
      dm – ìgbá (garden egg)
      rd – igbà (climbing rope)
   e. rm – agbọ́n (wasp/ honet)
      rd – agbọ̀n (basket)
      dm – àgbọ́n (a town)
      dr – àgbọn (coconut)
      dd – àgbọ̀n (chin)
   **f.** rm – irú (locust beans)
      dd – ìrù (tail)
   rd – irù (tsetse fly)

**IṢẸ́ ṢÍṢẸ – EXERCISE 2.0**

Fi àmì ohùn sí orí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí:

1. rrr- agbada (big fry pan)
2. mmmm – kẹtẹkẹtẹ (camel)
3. ddd – ṣekẹrẹ (rattle drum)
4. ddddd- akalamagbo (vulture)
5. dmrm – ikọkọrẹ (wateryam porridge)
6. dmr – okuta (stone)
7. rmmd – olongbo (cat)
8. rmrr – ọlọmọge (a young beautiful girl)
9. rmdrd – alantakun (spider)
10. ddm – ojola (pyton)

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSIGNMENT 2.0**

Fi àmì ohùn sí orí ọ̀rọ̀ wọ̀nyí:

1. aja (dog)
2. aja (roof)
3. owo (money)
4. owo (business)
5. owo (horn)
6. ọwọ (hand)
7. ọwọ (dew)
8. ọwọ (broom)
9. agbọn (wasp)
10. agbọn (basket)

**Ọ̀SẸ̀ KẸTA – WEEK 3**

**Ẹ̀SÌN ÌBÍLẸ̀ YORÙBÁ**

Ẹ̀sìn jẹ́ ọ̀nà tí àwọn Yorùbá ń gbà sin Ọlọ́run. Kí ẹ̀sìn ìgbàgbọ́ àti ẹ̀sìn mùsùlùmí tó dé àwùjọ wa ni àwọn Yorùbá ti gbà pé Ọlọ́run wà. Wọ́n gbà pé Ó wà ní ibi gbogbo àti pé Òun ni Ọ̀gá Ògo jùlọ. Kò sí òtítọ́ kan nínú ohun tí àwọn ènìyàn máa ń sọ pé abọ̀rìṣà ni àwọn Yorùbá. Lóòótọ́ àwọn Yorùbá ń bọ òrìṣà ṣùgbọ́n alágbàwí ni àwọn òrìṣà náà jẹ́ láàrin àwọn Yorùbá ati Ọlọ́run.

ORISI ESIN

1. Ẹ̀sìn ìgbàgbọ́ - Christian Relegion
2. Ẹ̀sìn Mùsùlùmí – Islamic religion
3. Ẹ̀sìn Júdà - Judaism
4. Ẹ̀sìn Híńdù - Hinduism
5. Ẹ̀sìn Búdà - Buddhism
6. Ẹ̀sìn gúrúmàrajì

**PÀTÀKÌ ẸSÌN LÁWÙJỌ YORÙBÁ**

1. Ẹ̀sìn máa ń jẹ́ kí ènìyàn ní ìmọ̀ nípa Ọlọ́run.
2. Ó ń jẹ́ kí á ní ìmọ̀ nípa òrìṣà mìíràn.
3. Ó máa ń jẹ́ kí ènìyàn ní ìwà ọmọlúwàbí.
4. Ó ń fún wa ní ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro ẹ̀dá.
5. Ó ń fún ni ní ìrètí lẹ́yìn ikú.
6. Ó máa ń jẹ́ kí ènìyàn gbàdúrà.
7. Ó ń fi ọkàn ẹni balẹ̀.
8. Ó ń dín ìwà ìbàjẹ́ kù láwùjọ.

**IṢẸ́ SÍṢE – EXERCISE 3.0**

Dí àlàfo wọ̀nyí pẹ̀lú ìdáhùn tí ó yẹ

1. ________ jẹ́ ọ̀nà tí àwọn ènìyàn ń gbà sin Ọlọ́run.
2. Alágbàwí ni àwọn _____ ____jẹ́ láàrin àwọn Yorùbá àti Ọlọ́run.
3. Christian religion túmọ̀ __________
4. Ẹ̀sìn Mùsùlùmí means ____________
5. Pàtàkì ẹ̀sìn láwùjọ Yorùbá ni pé ____________________________

**ORÚKỌ ỌLỌ́RUN NÍNÚ ÈDÈ YORÙBÁ**

1. Olódùmarè – The Almighty.
2. Adákẹ́dájọ́ – One who judges in silence.
3. Ọ̀gá Ògo – The King of Glory.
4. Ọba Àìrí – The Unseen God
5. Alèwílèṣe – One who says and does what He says.
6. Ọba àìkú – One who does not die.
7. Olú ọ̀run – The Mighty one in Heaven.
8. Ẹlẹ́dàá, Aṣèdá, Adẹ́dàá – The Creator
9. Ọba Ọrun – The King of Heaven.
10. Olúwa – The Lord

**ORÚKỌ TÍ ÀWỌN ẸYÀ MÌÍRÀN Ń PE ỌLỌ́RUN**

1. Hausa --- Ubangiji / Allah
2. Igbo------Chineke / Chukwu
3. Efik ------Abasi
4. Egun ----- Mawu
5. Edo-------Ozanobua
6. Itshekiri - - Oriitse
7. Tapa ------- Soko
8. Yoruba ------ Olorun , Olódùmarè.abbl

**ÀWỌN ÒRÌṢÀ ILẸ̀ YORÙBÁ**

1. Ògún -----the god of iron
2. Ṣàngó ---- the god of thunder
3. Orò̀ ------the night masquerade
4. Ọya ------ the goddess of River Niger
5. Egúngún ------ the spirit of our ancestors (masquerade)
6. Ifá / Ọ̀rúnmìlà ----- the god of divinity
7. Ọbàtálá ------- the god of creation

**ÌGBÀGBỌ́ YORÙBÁ NÍPA OLÓDÙMARÈ**

1. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ọkùnrin ni Ọlọ́run
2. Wọ́n gbàgbọ́ pé ọ̀run ni ilé rẹ̀.
3. Wọ́n gbàgbọ́ pé òun ló dá ayé àti ọ̀run pẹ̀lú ohun gbogbo tí ó wà nínú rẹ̀.
4. Wọ́n gbà pé ó tóbi ju gbogbo ẹ̀dá lọ.
5. Wọ́n gbàgbọ́ pé ó wà ní ibi gbogbo.
6. Wọ́n gbàgbọ́ pé kò sí ohun tí kò lè ṣe.

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSGNMENT 3.0**

1. **Kọ méjì nínú orúkọ tí àwọn Yorùbá ń pe Ọlọ́run sílẹ̀.**

| | |
|---|---|
| **1.** | **2.** |

2. **Dárúkọ márùn-ún nínú àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá.**

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| **1.** | **2.** | **3.** | **4.** | **5.** |

3. **Kí ni orúkọ tí àwọn ẹ̀yà wọ̀yí ń pe Ọlọ́run ?**

| **Itshekiri** | **Hausa** | **Ègùn** |
|---|---|---|
| | | |

**Ọ̀SẸ̀ KẸRIN – WEEK 4**

**ÌTÚPALẸ̀ ÌWÉ ÌTÀN ÀPILẸ̀KỌ**

**Ori Kin-in-ni iwe <u>Ikú Akọni</u>**

1. Ìwé yìí dálé orí ìlú Ajéìígbé tó ń sàn fún wàrà àti fàdákà.
2. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìlú ló máa ń jowú àlùmọ́nì tí Ọba Òkè fún ìlú náà.
3. Ìlú Àpésìn fi àrokò ogun ránṣẹ́ sí ìlú Ajéìígbé pé kí wọ́n yọ̀nda ilẹ̀ ojú odò fún àwọn bíbẹ́ẹ̀kọ́ àwọn yóò fi ogun ja ìlú náà.
4. Ọba (Kábíyèsí) àti àwọn ìjòyè ìlú Ajéìígbé ń jíròrò lórí àrokò ogun tí ìlú Àpésìn fi ránṣẹ́ sí wọn.
5. Ìlú Àpésìn jẹ́ ìlú alágbára, kò sí ìlú to ṣẹ́gun wọn rí.
6. Ọ̀tún ní kí àwọn yọ̀nda ilẹ̀ náà fún wọn.
7. Ìyálóde ní kí àwọn fi ẹ̀hónú hàn.
8. Kábíyèsí, Ọ̀sì àti Balógun fi ara mọ́ ọn (gbà) kí àwọn gbé ogun ti ìlú Àpésìn.
9. Èyí mú kí wọ́n pàrokò ogun sí wọn.

**Àwọn Ẹ̀dá Ìtàn**

1. Kábíyèsí – ọba ìlú Ajéìígbé.
2. Ọ̀tún – igbákejì ọba.
3. Òṣì – igbákẹta ọba.
4. Bológun – olórí ogun ìlú Ajéìígbé
5. Ìyálóde – olorí àwọn obìnrin ìlú Ajéìígbé.

**IṢẸ́ ṢÍṢE – EXERCISE 4.0**

**Dáhùn gbogbo ìbéèrè.**

1. **Ìwé Ikú Akọni dálé orí _________**

| Ans : |
|---|

2. **Àwọn ìlú tó ń bá ara wọn jà ni ______**

| Ans : 1. | 2. |
|---|---|

3. **Ìlú wo ló ń sàn fún wàrà àti fún oyin.**

| Ans : |
|---|

4. **Ìjòye mélòó ló wà ní ìlú Ajéìígbé?**

| Ans : |
|---|

5. **Dárúkọ ẹ̀dá ìtàn mẹ́rin nínú ìwé Ikú Akọni.**

| Ans : | | | |
|---|---|---|---|

**Orí Kejì ìwé Ikú Akọni**

1. Ọba àti àwọn ìjòyè ìlú Àpésìn jíròro lórí àrokò ogun tí ìlú Ajéìígbé pa ránṣẹ́.
2. Inú bí wọn fún ìwà àrífín tí ìlú Ajéìígbé hù.
3. Lẹ́yìn ọjọ méje wọ́n fi ogun ja ìlú Ajéìígbé wọ́n sì ṣẹ́gun wọn.
4. Wọ́n pa gbogbo ọmọ ogun ìlú Ajéìígbé.
5. Díẹ̀ nínú ọmọ ogun ìlú Àpésìn fi ara pa.
6. Wọ́n mú balogun ìlú Ajéìígbé láàyè wọ́n sì fi í sínú túbú (ẹ̀wọ̀n).
7. Wọ́n fún ọba ní ọjọ́ méje láti jọ̀wọ́ ara rẹ̀ bí bẹ́ẹ̀ kọ́ wọn yóò pa ìlú rẹ̀ run.
8. Ọba ìlú Ajéìígbé fún àwọn ìjòyè rẹ̀ ní ọjọ mẹ́ta láti wá ọ̀nà àbáyọ.

**Àwọn Ẹ̀dá Ìtàn orí kejì.**

Àwọn ìjòyè ìlú Àpésìn: Kábíyèsí, Ọ̀tún, Òṣì àti Balógun

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSIGNMENT 4.0**

1. Ìlú wo ló pa àrokò ránṣẹ́? Ìlú

| Ans : |
|---|

2. Ìlú Àpésìn fi ogun ja ìlú Ajéìígbé lẹ́yìn ọjọ́ _____

| Ans : |
|---|

3. Ìjòyè tí wọ́n mú láàyè ni ______

| Ans : |
|---|

4. Wọ́n fún ọba Ajéìígbé ni ọjọ́ mélòó láti jọ̀wọ́ ara rẹ̀?

| Ans : |
|---|

5. Àwọn ọmọ ogun tó fara pa ni àwọn ọmọ ogun ìlú

**Ọ̀SẸ̀ KARÙN-ÚN – WEEK 5**

**ÒǸKA YORÙBÁ: KÍKA 200 – 300 NÍ ÈDÈ YORÙBÁ**

| | |
|---|---|
| 200- ọgọ́wàá / igba<br>201= òkàn-lé-nígba<br>202= èjì-lé-nígba<br>203= ẹ̀tà-lé-nígba<br>204= ẹ̀rìn-lé-nígba<br>205= àrùn-dín-ẹ̀wálénígba<br>206= ẹ̀rìn-dín-ẹ̀wálénígba<br>207= ẹ̀tà-dín-ẹ̀wálénígba<br>208= èjì-dín-ẹ̀wálénígba<br>209= òkàn-dín-ẹ̀wálénígba<br>210= ẹ̀wálénígba / ẹ̀wá- dín-okòólénígba | 200 – ọgọ́wàá / igba<br>210 – ẹ̀wálénígba / ẹ̀wá dín okòólénígba<br>220 =okòólénígba<br>230 = ẹ̀wá-dín-òjílénígba / ọgbọ̀nlénígba<br>240 = òjìlénígba<br>250 = ẹ̀wá-dín-ọ̀tàlénigba / àádọ́ta-lé-nígba<br>260 = ọ̀tàlénígba<br>270 = ẹ̀wà-dín-ọ̀rìnlénígba / àádọ́rin-lé-nígba<br>280 = ọ̀rìnlénígba<br>290 = ẹ̀wá-dín-ọ̀ọ́dúnrún / àádọ́rùnún –lé-nígba<br>300 = oodunrun |

| **211 – 221** | **221 – 230** |
|---|---|
| 211 – òkàn-lé- ẹ̀wálénígba | 221 – òkàn-lé- okòólénígba |
| 212 – Èjì-lé- ẹ̀wálénígba | 222 – èjì-lé- okòólénígba |
| 213 – Ẹ̀ta-lé- ẹ̀wálénígba | 223 – ẹ̀ta lé- okòólénígba |
| 214 – Ẹ̀rin lé- ẹ̀wálénígba | 224 – ẹ̀rin-lé- okòólénígba |
| 215 – Àrún-dín- okòólénígba | 225 – àrún-dín-ọgbọ̀nlénígba. |
| 216 – Ẹ̀rin-dín- okòólénígba | 226 – ẹ̀rin-dín- ọgbọ̀nlénígba. |
| 217 – Ẹ̀tà-dín- okòólénígba | 227 – ẹ̀ta-dín- ọgbọ̀nlénígba. |
| 218 – Èjì-dín- okòólénígba | 228 – èjí-dín- ọgbọ̀nlénígba. |
| 219 – Ọ̀kàn-dín- okòólénígba | 229 – òkan-dín- ọgbọ̀nlénígba. |
| 220 – okòólénígba | 230 – ọgbọ̀nlénígba. |

**IṢẸ́ ṢÍṢE – EXCERCISE 5.0**

**Kọ 331 – 340 ní èdè Yorùbá.**

| | |
|---|---|
| **231** | |
| **232** | |
| **233** | |
| **234** | |
| **235** | |
| **236** | |
| **237** | |
| **238** | |
| **239** | |

| | |
|---|---|
| **240** | |

**241 – 260**

| **241 – 250** | **251 – 260** |
|---|---|
| **241 – òkànlé òjìlénígba** | **251 – òkàndín àádọ́ta lénígba** |
| **242 – èjìlé òjìlénígba** | **252 – èjìdín àádọ́ta lénígba** |
| **243 –ẹ̀tàlé òjìlénígba** | **253 – ẹ̀tàdín àádọ́ta lénígba** |
| **244 – ẹ̀rìnlé òjìlénígba** | **254 – ẹ̀rìndín àádọ́ta lénígba** |
| **245 – àrùndín àádọ́ta lénígba** | **255 – àrúndín ọ̀tàlénígba** |
| **246 – ẹ̀rindín àádọ́ta lénígba** | **256 –ẹ̀rìndín ọ̀tàlénígba** |
| **247 – ẹ̀tàdín àádọ́ta lénígba** | **257 – ẹ̀tàdín ọ̀tàlénígba** |
| **248 – èjìdín àádọ́ta lénígba** | **258 – èjìdín ọ̀tàlénígba** |
| **249 – òkàndín àádọ́ta lénígba** | **259 – òkàndín ọ̀tàlénígba** |
| **250 - àádọ́ta lénígba** | **260 – ọ̀tàlénígba** |

**IṢẸ́ ṢÍṢE – EXERCISE 5.1**

**Kọ 261 – 270 ní èdè Yorùbá**

| | |
|---|---|
| **261** | |
| **262** | |
| **263** | |
| **264** | |
| **265** | |
| **266** | |
| **267** | |
| **268** | |
| **269** | |
| **270** | |

**271 – 290**

| **271 – 280** | **281 – 290** |
|---|---|
| **271 – òkànlé àádọ́rinlénígba** | **281 – òkànlé ọ̀rìnlénigba** |
| **272 – èjìlé àádọ́rinlénígba** | **282 – èjìlé ọ̀rìnlénigba** |
| **273 – ẹ̀tàlé àádọ́rinlénígba** | **283 – ẹ̀tàlé ọ̀rìnlénigba** |
| **274 – ẹ̀rìnlé àádọ́rinlénígba –** | **284 – ẹ̀rìnlé ọ̀rìnlénigba** |
| **275 – àrùndín ọ̀rìnlénigba** | **285 – àrúndín àádọ́rùnlénígba** |
| **276 – ẹ̀rìndín ọ̀rìnlénigba** | **286 –ẹ̀rìndín àádọ́rùnlénígba** |
| **277 –ẹ̀tàdín ọ̀rìnlénigba** | **287 – ẹ̀tàdín àádọ́rùnlénígba** |
| **278 – èjìdín ọ̀rìnlénigba** | **288 – èjìdín àádọ́rùnlénígba** |
| **279 –òkàndín ọ̀rìnlénigba** | **289 – òkàndín àádọ́rùnlénígba** |
| **280 – ọ̀rìnlénigba** | **290 – àádọ́rùnlénígba** |

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSIGNMENT 5.0**

**Kọ 291 – 300 ní èdè Yorùbá.**

| | |
|---|---|
| **291** | |
| **292** | |
| **293** | |
| **294** | |
| **295** | |
| **296** | |
| **297** | |
| **298** | |
| **299** | |
| **300** | |

## ỌSẸ̀ KẸFÀ – WEEK 6

## GBÓLÓHÙN ÈDÈ YORÙBÁ

Gbólóhùn ni ẹyọ tàbí àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ tí ó ní ìtumọ̀ tí ó sì tẹ̀lé ìhun gírámà èdè Yorùbá. Bí àpẹẹrẹ

Kọ̀lá jẹ àgbàdo. (Kọ̀lá ate corn)

Ìdòwú sùn. (Ìdòwú slept)

Pàtẹ́wọ́. (Clap)

Àlàbà kọ́ ilé titun. (Àlàbá built a new house)

Àlàbí ra ọkọ̀ titun fún ọmọ rẹ̀. (Àlàbí bought a new car for his child)

Ó wá ṣùgbọ́n ó pẹ́ kí ó tó dé. (He came but he arrived late)

***ORÍṢI GBÓLÓHÙN***

1. Gbólóhùn Abọ́dé / ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀-ìṣe (simple sentence)
2. Gbólóhùn ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe. (Complex sentence)
3. Gbólóhùn alákànpọ̀. (Compound sentence)
4. Gbólóhùn oníbọ̀. (Complex complex sentence)

1. ***Gbólóhùn Ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀-ìṣe / Abọ́dé***. (Simple sentence)
   Èyí ni gbólóhùn tí kò ní ju ọ̀rọ̀ ìṣe kan lọ nínú ìhun rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ:
   i. Àlàbí kọ́ ilé. (Àlàbí built a house.)
   ii. Tàlàbí pa ejò ọká ńlá. (Tàlàbí killed a big viper.)
   iii. Kúnlé ra ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́. (Kúnlé bougt a car.)
   iv. Ọláwálé jẹ ọba lẹ́yìn ikú bàbá rẹ̀. (Olawale became the king after the demise of his father))
2. ***Gbólóhùn Ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe (Complex sentence)***
   Èyí ni gbólóhùn tí ó ní ọ̀rọ̀ ìṣe méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àpẹẹrẹ:
   i. Ìdòwú ra ẹ̀pà jẹ. (ìdòwú bought and ate groundnut.)

ii. Fọláṣadé gbé ọjà rẹ̀ lọ sí ọjà. (Folasade carried her goods and went to the market.)
iii. Kọ́láwọlé lé ọmọ rẹ̀ jáde. (Kọ́láwọlé chased his son out.)
iv. Wọ́n rí mi sá. (They saw me and ran away.)

**IṢẸ́ ṢÍṢẸ – EXERCISE 6.0**

**Kọ ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó wà nínú gbólóhùn wọ̀nyí sílẹ̀.**

| | Gbólóhùn | Orọ̀-ìṣe |
|---|---|---|
| 1. | Àlàbá jẹ iṣu àti ẹyin. | |
| 2. | Ṣadé ra bàtà titun. | |
| 3. | Kíkẹ́lọmọ ra ẹja tà ní ọjà ọba. | |
| 4. | Kòsókọ́ wá gbé ata lo si ìdí ẹ̀rọ. | |
| 5. | Àlàdé pàtẹ́wọ́. | |

### *3. GBOLOHUN ALAKANPO*

Eyi ni gbolohun meji tabi ju bee lo ti a fi oro asopo so di eyo kan. Bi apeere:

a. Idowu jeun amo ko yo.
b. Kolawole wa tabi ko wa.
c. Ojo pon omi, o fo abo, o si fo aso re.
d. Sade kii je isu ayafi iyan.

### *4. GBOLOHUN ONIBO*

Eyi ni gbolohun ti o ni olori awe gbolohun ati awe gbolohun afarahe

***a. Olori awe gbolohun – Main clause(independent clause)***

Eyi ni gbolohun ti o le da duro pelu itumo kikun. Bi apeere:

| | **Gbólóhùn Oníbọ̀** | **Olórí Awẹ́ Gbólóhùn** | **Awẹ́ Gbólóhùn Afarahẹ** |
|---|---|---|---|
| 1. | Bọ̀dé kọ́ ilé tí ó tóbi. | Bọ̀dé kọ́ ilé. | Tí ó tóbi. |
| 2. | Àjàlá ra dòdò àti ìrẹsì tí ó fẹ́ jẹ. | Àjàlá ra dòdò àti ìrẹsì. | Tí ó fé jé. |
| 3. | Ó dára kí akẹ́kọ̀ọ́ múra sí ẹ̀kọ́ rẹ̀. | Ó dára. | Kí akẹ́kọ̀ọ́ múra sí ẹ̀kọ́ rẹ̀. |
| 4. | Kò yẹ kí á máa oògùn olóró | Kò yẹ. | Kí a mu oògùn olóró. |
| 5. | Mo mọ̀ pé ọ̀gá fẹ́ràn mi. | Mo mọ̀. | Pé ọ̀gá fẹ́ràn mi. |

**IṢẸ́ ṢIṢẸ – EXERCISE 6.1**

**Pín gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí sí olórí awẹ́ gbólóhùn àti awẹ́ gbólóhùn afarahẹ.**

Answer:

| | **Gbólóhùn Oníbọ̀** | **Olórí Awẹ́ Gbólóhùn** | **Awẹ́ Gbólóhùn Afarahe** |
|---|---|---|---|

| | | | |
|---|---|---|---|
| 1. | Ìdòwú wá igi tí ó fẹ́ fi dá iná. | | |
| 2. | Ìyábọ̀ ra bàtà tí ó fé wọ̀. | | |
| 3. | Ó yẹ kí ọmọ gbọ́ràn sí òbí rẹ̀ lẹ́nu. | | |
| 4. | Àjàyí jẹun kí ó tó lọ sí ọjà. | | |
| 5. | Ọ̀yà tí bàbá ọdẹ pa tóbi púpọ̀. | | |

***b. Awé gbólóhùn afarahẹ- Subordinate clause (dependent clause)***

Èyí ni gbólóhùn tí kò lè dá dúró pẹ̀lú ìtumọ̀ kíkún àyàfi tí ó bá fi ara hẹ olórí awẹ́ gbólóhùn. Bí àpẹẹrẹ:

| | Gbólóhùn Oníbọ̀ | Olórí Awẹ́ Gbólóhùn | Awẹ́ Gbólóhùn afarahẹ |
|---|---|---|---|
| 1. | Bí mo bá rí ìwé ìpè màá wá sí ìpàdé náà. | Màá wá sí ìpàdé náà. | Bi mo ba ri iwe ipe |
| 2. | Ọkọ̀ tí Bọ̀dé rà dára púpọ̀. | Ọkọ̀ dára púpọ̀. | Tí Bọ̀dé rà |
| 3. | Kí ìdánwò tó dé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ka ìwé wọn. | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ka ìwé wọn. | Kí ìdánwò tó dé. |
| 4. | Aṣọ tí Àìná wọ̀ dọ̀tí. | Aṣọ dọ̀tí. | Tí Àìná wọ̀. |
| 5. | Wọ́n ń pariwo bí ó ṣe wù wọ́n. | Wọ́n ń pariwo. | Bí ó ti wù wọ́n. |

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSIGNMENT 6.0**

Parí àtẹ ìsàlẹ̀ yìí pẹ̀lú gbólóhùn tí ó yẹ

| | Gbólóhùn Oníbọ̀ | Olórí Awẹ́ Gbólóhùn | Awẹ́ Gbólóhùn afarahẹ |
|---|---|---|---|
| 1. | | Àlàbá ra ọkọ̀ | Kí ó took ilé |
| 2. | Ajá tí ó tóbi pọ̀ ní Oǹdó. | | Tí ó tóbi. |
| 3. | Wọ́n ń ṣiṣẹ́ kí wọ́n lè lówó lọ́wọ́. | Wọ́n ń ṣiṣẹ́ | |
| 4. | | Mo gbọ́. | pé o bímọ titun. |
| 5. | Kò yẹ kí á má abá ara wa ja | | |

**Ọ̀SẸ̀ KEJE - WEEK 7**

**ÀṢÀ ÌRANRA-ẸNI-LỌ́WỌ́ NÍLẸ̀ YORÙBÁ LÁYÉ ÀTIJỌ́**

Àṣà yìí jẹ́ ọ̀nà tí àwọn Yorùbá ń gbà ran ara wọn lọ́wọ́ nínú iṣẹ́ tí wọn kò lè dá ṣe láyé àtijọ́. Oríṣi ọ̀nà méjì ni a lè pín ìranra-ẹni-lọ́wọ́ sí:

1. Ìranra-ẹni-lọ́wọ́ nípa iṣẹ́
2. Ìranra-ẹni-lọ́wọ́ nípa owó.

1. Ìranra ẹni lọ́wọ́ nípa iṣẹ́

a. Àáró : Èyi máa ń wáyé nígbà tí àwọn ènìyàn bíi méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ bá kó ara wọn jọ láti máa ṣiṣẹ́ nínú oko ara wọn ní mọ̀kàn-mọ̀kàn tí oyèé kàn. Bí wọ́n bá lọ sí oko ẹnì kìn-ín-ní

ni òní wọn yóò lọ sí oko ẹnìkejì ní ọ̀la títí yóò fi kárí. Dandan ni kí ẹni tí ó ti gba ààró san án padà. Kò pọn dandan kí ẹni tí ààró kàn wá oúnjẹ fún àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀.

b. Àrokodóko : Èyí sábà máa ń wáyé láàrin àwọn ènìyàn méjì tí oko wọn kò jìnnà sí ara wọn. Bí wọ́n bá lọ sí oko ẹnìkan ní àárọ̀ wọ́n yóò lọ sí oko ẹnìkejì ní ìrọ̀lẹ́.

c. Ọ̀wẹ̀: Iṣẹ́ tí ó nílò ọ̀pọ̀ ènìyàn ni èyí wà fún. Èyí máa ń wáyé nígbà tí a bá fẹ́ ṣe iṣẹ́ ńlá bíi ilé kíkọ́, ọ̀nà yíyẹ̀, kànga gbígbẹ́, oko àna, gbígbé afárá kọjá lórí odò tàbí ìgbẹ́ ọdún. Dandan ni kí ẹni tí ó bẹ ọ̀wẹ̀ pèsè oúnjẹ fún àwọn tí ó bẹ̀ lọ́wẹ̀.

d. Ẹ̀bẹ̀ṣẹ́: Èyí wọ́pọ̀ láàrin àwọn obìnrin pààpàá ní àsìkò ayẹyẹ bíi ìsọmọlórúkọ, oyè jíjẹ, ìṣílé, ìgbeyàwó tàbí òkú àgbà. Wọ́n lè bẹ ara wọn láti wá oúnjẹ, wá igi nínú oko tàbí pọn omi fún ìnáwó. Dandan ni kí á tọ́jú oúnjẹ fún ẹni tí a bẹ̀ ní ẹ̀bẹ̀ṣẹ́.

### IṢẸ́ ṢIṢE – EXERCISE 7.0

Dáhùn gbogbo ìbéèrè. Circle the correct answer.

1. Àrokodóko wọ́pọ̀ láàrin àwọn ènìyàn ________ A. méjì B. mẹ́ta C. mẹ́rin.
2. Dandan ni kí ènìyàn pèsè oúnjẹ nínú ________ A. ààró B. ẹ̀bẹ̀ṣẹ́ C. àrokodóko.
3. Mọ̀nkàn-mọ̀kàn tí oyèé kàn jẹyọ nínú _______ A. ọ̀wẹ̀ B. ẹ̀bẹ̀ṣẹ́ C. ààró.
4. Èyí tí ó nílò ọ̀pọ̀ ènìyàn ni ________ A. àrokodóko B. ẹ̀bẹ̀ṣẹ́ C. ọ̀wẹ̀
5. Èwo ló wọ́pọ̀ láàrin àwọn obìnrin? _________ A. ẹ̀bẹ̀sẹ́ B. ààró. C. ọ̀wẹ̀

### ÀǸFÀÀNÍ ÀṢÀ ÌRANRA-ẸNI-LỌ́WỌ́

a. Ó máa ń jẹ́ kí á ṣe iṣẹ́ púpọ̀ ní àsìkò péréte.
b. Ó máa ń jẹ́ kí ìrẹ́pọ̀ àti ìfẹ́ wà láàrin àwùjọ
c. Kìí jẹ́ kí ènìyàn ṣe ọ̀lẹ.

***2. ÀṢÀ ÌRANRA-ẸNI-LỌ́WỌ́ NÍPA OWÓ***

Èyí jẹ́ ọ̀nà tí àwọn Yorùbá ń gbà fi owó ran ara wọn lọ́wọ́. Bí àpẹẹrẹ:

1. ***ÀJỌ***: Àjọ jẹ́ ọ̀nà tí a ń gbà kó owó jọ sí ọwọ́ ẹnìkan ní ojoojúmọ́ pẹ̀lú àdéhùn láti gba irú owó bẹ́ẹ̀ ní ìparí oṣù. Àwọn alájọ ojúmọ́ máa ń lọ láti ilé dé ilé láti gba àjọ. Alájọ ni ó ni owó tí ènìyàn bá kọ́kọ́ dá ní ìbẹ̀rẹ̀ oṣù.
2. ***Èsúsú*** : Èsúsú fi ara pẹ́ àjọ ṣùgbọ́n ìyàtọ̀ ibẹ̀ ni pé iye owó tí ènìyàn bá dá ni yóò kó. Tí wọ́n bá dá owó ní ọ̀sẹ̀ yìí wọn yóò kó o fún ẹnì tí èsúsú kàn. Báyìí ni wọn yóò máa ṣe títí àjọ yóò fi kárí.
3. ***Sogúndogójì*** :̀ Èyí máa ń wáyé nígbà tí a bá san ìlọ́po méjì owó tí a yá.
4. ***Owó Èlé*** : Èyí máa ń wáyé nígbà tí a bá san èlé lórí owó tí a yá.
5. ***Àràdoṣù*** : Èyí máa ń wáyé nígbà tí a bá san owó ọjà tí a rà ní ìparí oṣù.
6. ***Ìfidógò*** : Èyí máa ń wáyé nígbà tí a bá fi nǹkan ìní ẹni bíi aṣọ, ilé, ilẹ̀, oko abbl ṣe ìdúró fún owó tí a yá.
7. ***Ìwọ̀fà*** : Èyí máa ń wáyé nígbà tí a bá fi ọmọ ẹni ṣe ìwọ̀fà lọ́dọ̀ olówó. Irú ọmọ bẹ́ẹ̀ á máa ṣe iṣẹ́ sin olówó rẹ̀ títí àwọn òbí rẹ̀ yóò fi rí owó tí wọ́n yá san padà. Ènìyàn lè fi ara rẹ̀ ṣọ̀fà.

8. ***Gbàmí-o-rà-mí :*** Èyí máa ń ṣẹlẹ̀ nígbà tí kò bá sí owó láti tọ́jú aláìsàn. Àwọn òbí ọmọ bẹ́ẹ̀ lè mú un lọ sí ọ̀dọ̀ oniṣègùn fún ìtọ́jú pẹ̀lú àdéhùn pé kí onísègùn fi ṣe aya bí ara rẹ̀ bá ti yá pàápàá bí ó bá jẹ́ obìnrin. Bí ó bá jẹ́ ọkùnrin wọ́n lè sọ irú ẹni bẹ́ẹ̀ di ẹrú.
9. ***Ọjà àwìn :*** Èyí máa ń wáyé nígtbà tí ènìyàn bá ra ọjà lọ́wọ́ ọlọ́jà pẹ̀lú àdéhùn láti san án padà nígbà tí o bá rí owó san.

### ÀṢÀ ÌRANRA-ẸNI-LỌ́WỌ́ LÓDE ÒNÍ

1. **Ẹgbẹ́ Aláfọwọ́sowọ́pọ̀** : Èyí máa ń wáyé nígbà tí àwọn ẹgbẹ́ tí a mọ̀ sí ẹgbẹ́ alájẹsẹ́kù bá kó ara wọn jọ. Wọn yóò yan olóyè ẹgbẹ́ wọn yóò sì máa fi owó pamọ́ bí agbára wọn bá ṣe mọ. Ènìyàn lè yá ìlọpo mẹ́ta owó tí ènìyàn bá fi sínú ẹgbẹ́. Ẹni tí kìí bá ṣe ọmọ ẹgbẹ́ kò lè ní àǹfààní láti yá owó.
2. **Ètò Adójútòfò** : Èyí máa ń wáyé nígbà tí ènìyàn bá fi orúkọ sílẹ̀ pẹ̀lú ilé iṣẹ́ adójútòfò. Irú ẹni bẹ́ẹ̀ yóò máa san owó ní oṣooṣud sí àpò àjọ adójutòfò pẹ̀lú àdéhùn pé bí nǹkan ǹ́í ẹni bí  ilé, ọkọ̀, oko, tàbí ile-iṣẹ́ bá jóná tàbí bàjẹ́, wọn yóò bá irú ẹni bẹ́ẹ̀ ra òmíràn tàbí kí wọ́n tún èyí tí ó bàjẹ́ ṣe.
3. **Ilé Ìfowópamọ́** : Èyí máa ń wáyé nígbà tí ènìyàn bá fi orúkọ sílẹ̀ ní ilé ìfowópamọ́. Irú owó tí a fí pamọ́ bẹ́ẹ̀ máa ń ní èlé lẹ́yìn oṣù tàbí ọdún kan. Ènìyàn lè yá owó ní ilé ìfowópamọ́. Kí ènìyàn tó lè yá owó ní ilé ìfowópamọ́ ó gbọ́dọ̀ fi ohun ìní rẹ̀ ṣe ìdúró.
4. **Owó Ìfẹ̀yìntì Lẹ́nu Iṣẹ́** : Ní ayé òde òní bí ènìyàn bá ti wọ iṣẹ́ ni yóò ti máa fi díẹ̀ díẹ̀ pamọ́ nínú owó rẹ̀ ní oṣooṣù. Ẹni tí ó bá gbani ṣíṣẹ́ náà a máa fi tiwọn kún un ní oṣooṣù. Irú owó bẹ́ẹ̀ ni ènìyàn máa ń dé bá nígbà tí ó bá fi ẹ̀yìn tì lẹ́nu iṣẹ́.

### IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSIGNMENT 7.0

1. Dárúkọ ọ̀nà márùn-ún tí àwọn Yorùbá ń gbà fi owó ra ara wọn lọ́wọ́.
   a. ____________________________________________
   b. ____________________________________________
   c. ____________________________________________
   d. ____________________________________________
   e. ____________________________________________
2. Tọ́ka sí ọ̀nà mẹ́ta tí àwọn ènìyàn ń gbà ran ara wọn lọ́wọ́ láyé òde òní.
   a. ____________________________________________
   b. ____________________________________________
   c. ____________________________________________

**Ọ̀sẹ̀ Kẹjọ – Week 8**

**ỌJỌ́ TÓ WÀ NÍNÚ Ọ̀SẸ̀**

| | Yorùbá | English |
|---|---|---|
| 1. | Ọjọ́ Àìkú | Sunday |
| 2. | Ọjọ́ Ajé | Monday |
| 3. | Ọjọ́ Ìṣégun | Tuesday |
| 4. | Ọjọ́’Rú | Wednesday |
| 5. | Ọjọ́’Bọ | Thursday |
| 6. | Ọjọ́ Ẹtì | Friday |
| 7. | Ọjọ́ Àbámẹ́ta | Saturday |

**OṢÙ TÓ WÀ NÍNÚ ỌDÚN**

| | Yorùbá | English |
|---|---|---|
| 1. | Ṣẹ̀ẹrẹ | January |
| 2. | Èrèlé | February |
| 3. | Ẹrẹ́nà | March |
| 4. | Igbe | April |
| 5. | Èbìbí | May |
| 6. | Okúdù | June |
| 7. | Agẹmọ | July |
| 8. | Ogún | August |
| 9. | Ọwẹ́wẹ̀ | September |
| 10. | Ọ̀wàrà | October |
| 11. | Belú | November |
| 12. | Ọ̀pẹ | December |

**IṢẸ́ ṢÍṢE – EXERCISE 8.0**


Dáhùn gbogbo ìbéèrè. (Shade the correct option)

| | | **A** | **B** | **C** |
|---|---|---|---|---|
| 1. | Ọjọ́ ajé means ___ A. Sunday B. Saturday C. Monday | | | |
| 2. | Thursday túmọ̀ sí ọjọ́___ A. Ajé B. Àìkú C. ‘Bọ | | | |
| 3. | Oṣù Agẹmọ ni _____ A. July B. June C. August | | | |
| 4. | Kí ni oṣù Ọctober ? A. Belú B. Ọ̀wàrà C. Òpẹ | | | |
| 5. | 5th, December means ọjọ́ __ oṣu__ A. karùn-ún, Ọ̀pẹ B. kẹfà, Èrèlé C. kẹta, Erẹ́nà | | | |

**SÍSỌ BÍ OJÚ ỌJỌ́ ṢE RÍ**

1. Òjò sú – Rain cloud is forming
2. Atẹ́gún ń fẹ́ – The wind is blowing.
3. Òjò fẹ́ rọ̀ – It is about to rain.
4. Òòrùn ń ràn – The sun is shining.
5. Òòrùn mú – The sun is hot.
6. Ooru mú – There is heat.
7. Otútù mú – The weather is cold.
8. Ọyẹ́ mú – There is hammattan.
9. Ààrá ń sán – The thunder is striking.

**SÍSỌ IYE AGOGO TÓ LÙ**

| | |
|---|---|
| 1. Aago kan<br> | 2. Aago mẹ́ta àbọ̀<br> |
| 3. Aago méje kọjá ìṣẹ́jú márùndínlógún<br> | 4. Aago mẹ́fà ku ogún ìṣẹ́jú.<br> |

.

**IṢẸ́ ṢÍṢE – EXERCISE 8.1**

**Aago mélòó ló lù? Tell the time in Yorùbá Language.**

1. 3 o'clock ________________________________________
2. 5.30 ____________________________________________
3. 4 minutes past 6 o'clock. __________________________
4. 10 minutes after 8 o'clock__________________________
5. 7 minutes to 12 o'clock.____________________________

**Ìlò AM àti PM ní èdè Yorùbá.**

| | |
|---|---|
| 12am – aago méjìlá òru | 12pm – aago méjìlá ọ̀sán. |
| 1am – aago kan òru | 1pm – aago kan ọ̀sán |
| 2am – aago méjì òru | 2pm – aago méjì ọ̀sán |
| 3am – aago mẹ́ta òru | 3pm – aago mẹ́ta ọ̀sán |
| 4am – aago mẹ́rin ìdájí | 4pm – aago mẹ́rin ìrọ̀lẹ́. |
| 5am – aago márùn-ún ìdájí | 5pm – aago márùn-ún ìrọ̀lẹ́ |
| 6am – aago mẹ́fà ìdájí | 6pm – aago mẹ́fà ìrọ̀lẹ́ |
| 7am – aago méje àárọ̀ | 7pm – aago méje alẹ́ |
| 8am – aago méjọ àárọ̀ | 8pm – aago méjọ alẹ́ |
| 9am – aago mẹ́sàn-án àárọ̀ | 9pm – aago mẹ́sàn-án alẹ́ |
| 10am – aago mẹ́wàá àárọ̀ / ìyálẹ̀ta | 10pm – aago mẹ́wàá alẹ́ |
| 11am – aago mọ́kànlá àárọ̀ / ìyálẹ̀ta | 11pm – aago mọ́kànlá alẹ́ |

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSIGNMENT 8.0.**

**Sọ iye agogo tó lù ní èdè Yorùbá. Telling the time in Yorùbá, Write your answer in the box provided.**

| | |
|---|---|
| 1. 12 am | |
| 2. 3:30 pm | |
| 3. 2 minutes past 4 o'clock | |
| 4. 6:20 pm | |
| 5. 8am | |
| 6. Quter to ii o'clock. | |

**Ọ̀SẸ̀ KẸSÀN-ÁN - WEEK 9.**

**Orí kẹta ìwé Ikú Akọni**

1. Ọba ìlú Ajéìígbé jókòó ni ori ibùsùn rẹ̀ ó ń ronú.
2. Olorì, ìyàwó rẹ̀ wá bá a lati tù ú ninu lori ọ̀rọ̀ ìlú.
3. Láìpẹ́ àwọn ìjòyè ránṣẹ́ sí ọba kí ó wá sí ààfin.
4. Ọba béèrè lọ́wọ́ wọn bóyá wọ́n ti rí ọ̀nà àbáyọ.
5. Àwọn ìjòyè fi ọkàn ọba balẹ̀ pé àwọn ti rí ọnà àbáyọ.
6. Fábìyí ní òun yóò gbé orí ọba ìlú Àpésìn wá bá ọba ní ààfin.
7. Fábìyí ṣèlérí pé kí wọn fún òun ní ọjọ́ mẹ́ta.
8. Ọba ṣèlérí láti dá ohun ìní rẹ̀ sí méjì tí yóò sì kó ìdá kan fún Fábìyí bí ó bá lè ṣẹ́gun ìlú Àpésìn.

**Orí Kẹrin**

1. Fábìyí gbé ogun ja ìlú Àpésìn ó sì ṣẹ́gun.
2. Ó pa ìlú náà run ó sì gbé orí ọba wọn sínú igbá wá fún ọba ìlú Ajéìígbé.
3. Gbogbo ìlú bẹ̀rẹ̀ sí yọ ayọ̀ ìṣẹ́gun.

4. Ọba mú ìlérí rẹ̀ ṣẹ. Ó pín ohun ìní rẹ̀ sí méjì ó sì kó ìdá kan fún Fábìyí.
5. Lẹ́yìn náà ọba pèsè jíjẹ àti mímu fún gbogbo ará ìlú.

**Àwọn ẹ̀dá ìtàn**

1. Ọba ìlú Aéìígbé
2. Àwọn ìjòyè
3. Fábìyí

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSIGNMENT 9.0**

Dí àlàfo wọ̀nyí pẹ̀lú ìdáhùn tí ó yẹ.

1. Ọba ìlú Ajéìígbé jókòó lórí ___________________
2. Ìyàwó ọba ìlú Ajéìígbé ni _____________
3. Àwọn ___________ ránṣẹ́ sí ọba.
4. ______ ṣèlérí láti ṣẹ́gun ìlú ÀpeMsìn.
5. Ọjọ́ mélòó ni Fábíyìí fún àwọn ará ìlú ? Ọjọ́ __________

**ÀWỌN OHUN Ọ̀GBÌN ÀTI IRÈ OKO**

| S/N | Irè Oko | Oúnjẹ tí a lè rí lára wọn |
|---|---|---|
| **1.** | **Iṣu – yam**<br>**Kókò – kokoyam**<br>**Ànọ̀mọ́ – water yam**<br>**Èsúrú – bitter yam** | **Iyán – pounded yam**<br>**Èlùbọ́ – yam powder.**<br>**Àmàlà – food made from yam powder.**<br>**Àsáró – yam porridge.**<br>**Dùǹdú – fried yam.**<br>**Iṣu sísun – roasted yam.**<br>**Ọ̀jọ̀jọ̀ – yam cake.**<br>**Iṣu sísè – boiled yam.** |
| **2.** | **Àgbàdo – corn**<br>**Ọkà bàbà – millet**<br>**Jero Genine corn** | **Àgbàdo sisè / Lamńgbé – cooked corn**<br>**Àgbàdo sísun – roasted corn.**<br>**Àbàrí – móín-móín made of fresh corn.**<br>**Ègbo – corn pudy**<br>**Gúgúrú – pop corn.**<br>**Sapala – cooked corn.**<br>**Ògì – processed corn for pap.**<br>**Ẹ̀kọ – food made from corn.**<br>**Àgídí**<br>**Ẹ̀kọ jíjẹ**<br>**Ẹ̀kọ mímu.** |
| **3.** | **Ẹ̀gẹ́ / gbágùúdá – cassava.** | **Gàrí – food made from**<br>**Ẹ̀bà – food made from gàrí.**<br>**Fùùfú – food made from cassava.**<br>**Púpurú – food made from cassava.**<br>**Èkùbọ́ láfún – cassava powder.**<br>**Ọkà Láfún – food made from cassava powder.** |

| | | |
|---|---|---|
| **4.** | **Ẹ̀wà – beans** | **Mọ́ín-mọ́ín – food made from beans**<br>**Àkàrà – beans cake**<br>**Gbẹ̀gìrì – beans soup**<br>**Àdàlú – mixture of beans and corn**<br>**Èkuru – food made from beans.**<br>**Mọ́nu/ Jógí – white mọ́ín-mọ́ín** |
| **5.** | **Ẹ̀pà – groundnut** | **Kúlíkúlí – groundnut cake.**<br>**Ẹ̀pà yíyan – roasted groundnut.**<br>**Ẹ̀pà sísè – cooked ground nut.** |
| **6.** | **Ọ̀gẹ̀dẹ̀ – plantain** | **Èlùbọ́- plantain powder**<br>**Àmàlà ọ̀gẹ̀dẹ̀ – food made from plantain powder**<br>**Ìpékeré – plantain chips**<br>**Bọ̀ọ̀lì – roasted plantain**<br>**Dòdò – fried plantain.** |

**Èso – Fruits**

1. **Òróǹbó / Ọsàn – orange**
2. **Ìbẹ́pẹ – pawpaw**
3. **Ọ̀pẹ òyìnbó – pineapple**
4. **Ọ̀gẹ̀dẹ̀ wẹ́wẹ́ – banana**
5. **Máńgòrò – mango**
6. **Àgbálùmọ̀ – cherry nut**
7. **Ìgbá – garden egg**

**IṢẸ́ ṢÍṢẸ – EXERCISE 9.0**

1. **Dárúkọ oúnjẹ márùn-ún tí a lè rí láti ara ọ̀kọ̀kan àwọn oúnjẹ wọ̀nyí:**
   a. **Kókò (a) _______ ____(b)__________(d)__________(e)___________(ẹ)______**
   b. **Ọ̀gẹ̀dẹ̀ (a)___________(b)__________(d)__________(e)___________(ẹ)__________**

| | |
|---|---|
| **ISORI OUNJE**<br>1. Ounje Afaralokun --- Carbohydrate:<br>Iyan – pounded yam<br>Eba – food made fron gari<br>Amala – food made from yam powder<br>Fuufu – food made from cassava<br>Egbo – food made from corn<br>Isu – yam<br>Gaari – food made from cassava<br>Asaro – yam porridge<br>Adalu – mixture of beans and coen<br>Koko - cocoyam | 3. Ounje Asemiro – Vitamins<br>Ogede – banana<br>Orombo – orange<br>Ope oyinbo – pineapple<br>Efo / ewebe – vegetables<br>Ibepe – pawpaw<br>4. Ounje Oloraa – fat and oil<br>Epo pupa – palm oil<br>Ororo – vegetable oil<br>Eran elede – pork meat<br>Eran oloraa – fatty meat<br>Ora eran – fat from meat<br>Epa – grandnut |

| | |
|---|---|
| 2. Ounje Amaradan --- Protein<br>Ewa – beans<br>Eyin – egg<br>Eja - fish<br>Eran – meat<br>Ede – crayfish<br>Moin-moin – food made from beans<br>Akara – beans cake | Egusi – melon<br>5. Ounje Oniyo – Mineral salt<br>Iyo – salt<br>Magi – maggi<br>Eso – fruits |

**Anfaani Ounje**

1. Ounje a maa fun ni ni okun ati agbara.
2. Ounje a maa mu eniyan dagba.
3. Laisi ounje eniyan ko le wa laaye.
4. Ounje maa n dena aisan lara eniyan.

**Itoju ounje ajeseku**

1. Ounje sisa
2. Ounje didin
3. Ounje sise
4. Ounje sisun.
5. Ounje yiyan.

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSIGNMENT 9.0**

**1. Dárúkọ oúnjẹ afaralókun márùn-ún ní èdè Yorùbá.**

**a.** ___________________________________
**b.** ___________________________________
**c.** ___________________________________
**d.** ___________________________________
**e.** ___________________________________

**ỌSẸ̀ KẸWÀÁ – WEEK 10**

**AAYAN OGBUFO ELEYO ORO**

| | **English** | **Yoruba** |
|---|---|---|
| | Education | Eko |
| | School | Ile-eko |
| | Teacher | Oluko |
| | Student | Akekoo |
| | Examination | Idanwo |
| | Book | Iwe |
| | Duster | Dusita |
| | Parent | Obi |

| | | |
|---|---|---|
| | Principal | Oga agba |
| | Holiday | Isinmi |
| | Assignment | Ise asetilewa |
| | Test | Idanwo ranpe |
| | Whiteboard | Patako ikowe |
| | Ruler | Rula |
| | Eraser | Iresa |
| | School uniform | Aso ile-eko |
| | School sandal | Bata ile-eko |
| | Hostel | Ile awon akekoo |
| | School hall | Gbongan ile-eko |
| | Library | Yaara ikowepamosi |

**ÌTẸSÍWÀJÚ GBÓLÓHÙN**

1. **Gbolohun Ibeere**

Eyi ni gbolohun ti a n lo lati beere nnkan ti a fem o lowo elomiran.
Awon atoka ibeere ni :

a. Ta – who Ta lo n wa?
b. Ki – whatKi ni o n wa?
c. Ewo – which  Ewo ni o fe ninu awon mejeeji
d. Bawo – howBawo ni o se fe si?
e. Meloo – how many   Orombo meloo ni Olu mu?
f. Ibo – where  Ibo ni ona oja?
g. Igba wo – when Iba wo ni Bola lo?
h. Ewo – which   Ewo ni o fe?
i. Nko – where   - Baba nko?
j. Da – where   - Sola da?

2. **Gbolohun Ase**

Eyi ni gbolohun ti a fi n pase fun eniyan lati se ohun ti a fe. Bi apeere:

a. Dide
b. Jokoo
c. Sere
d. Patewo.
e. Fun mi ni biro re
f. Wa ni ola.
g. Ma pariwo mo etc.

3. **Gbólóhùn Ìyísódì**

Èyí ni gbólóhùn tí a fi máa ń yí gbólóhùn mìíràn sí òdí tàbí ìdàkejì. Àwọn atọ́ka ìyísódì ni: kò, kọ́, kìí, má abbl. Bí àpẹẹrẹ

| | Gbólóhùn | Gbólóhùn ìyísódì |
|---|---|---|
| 1. | Jídé pa eku. | Jídé kò pa eku. |
| 2. | Àlàbá mu omi. | Àlàbá kò mu omi. |
| 3. | Ṣọlá ń fọ abọ́. | Ṣọlá kò fọ abọ́. |
| 4. | Adé fẹ́ ra bàtà. | Adé kò fẹ́ ra bàtà. |
| 5. | Fẹ́mi máa ń kọ orin. | Fẹ́mi kìí kọ orin. |
| 6. | Ṣadé á jẹ ẹja. | Ṣadé kò ní jẹ ẹja. |
| 7. | Kúnlé á lọ sí ọjà. | Kúnlé kò ní lọ sí ọjà. |
| 8. | Túndé a máa lu ìlù. | Túndé kìí lu ìlù. |
| 9. | Òjó ni ó pa eku. | Òjó kọ́ ni ó pa eku. |
| 10. | Pariwo. | Má pariwo. |
| 11. | Sọ̀rọ̀ sókè. | Má sọ̀rọ̀ sókè. |

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSIGNMENT 10.0**

Dárúkọ irú gbólóhùn tí ọ̀kọ̀ọ̀kan gbólóhùn wọ̀nyí jẹ́.

1. Ta ni ó ni ìwé orí tábìlì? ________________________
2. Sáré wá. ______________________________________
3. Àjàlá ńkọ́?_______________________________________
4. Kọ́mọláfẹ́ kò wá sí ilé-ẹ̀kọ́. _________________________
5. Ṣọlá kìí jẹ ẹ̀bà. _____________________________________

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSIGNMENT 10.1**

Fa ìlà sí atọ́ka ìyísódì nínú gbólonùn wọ̀nyí.

1. Àlàbá kò mọ ìwé púpọ̀.____________________
2. Ṣadé kìí jẹ ẹja gbígbẹ.______________________
3. N kò lọ sí Ìbàdàn mọ́.______________________
4. Má pariwo sí wa létí.______________________
5. Sọ fún ọ̀rẹ́ rẹ pé o kò ṣeré mọ́.______________

**ÀWỌN ÌBÉÈRÈ FÚN ÌGBÁRADÌ – LIKELY EXAMINATION QUESTIONS**
**YORUBA LANGUAGE CLASS: JSS 2 DURATION: 1 ½ HOUR**
**SECTION A : OBJECTIVES (60 MARKS)**
**INSTRUCTION: ANSWER ALL QUESTIONS**

**Ka ayoka isale yii ki o si dahun ibeere ti o tele e.**

Ìlú Ajékìígbé jẹ ìlú tó ń sàn fún wàrà àti fún oyin. Orúkọ ọba ìlú Ajékìígbé ni Májẹ̀kódùnmí. Ìlú Àpésìn máa ń jowú ìlú Ajékìígbé nítorí nǹkan àlùmọ́ọ́nì tí Ẹlẹ́dàá fún wọn. Ọba ìlú Àpésìn tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Ìjàkòdọlà ránṣẹ́ ogun sí ìlú Ajékìígbé. Ìjàkòdọlà fún ìlú Ajékìígbé ní ọjọ́ méje láti jọ̀wọ́ àlùmọ́ọ́nì wọn bíbẹ́ẹ̀kọ́ wọn yóò gbé ogun ja ìlú náà.

Ọba ìlú Ajékìígbé pe àwọn ìjòyè rẹ̀ sí ìpàdé pàjáwìrì. Balógun, Ọ̀tún, Òṣì, Aṣípa àti ìyálóde gbìmọ̀ pọ̀ wọ́n bẹ Fábíyìí lọ́wẹ̀ láti gbógun ti ìlú Àpésìn. Májẹ̀kódùnmí ṣèlérí láti kó ìdá kan dúkìá rẹ̀ fún Fádèyí bí ó bá lè ṣẹ́gun ìlú Àpésìn.

Ọjọ́ karùn-ún ni Fábíyìí gbógun ti ìlú Àpésìn ó sì ṣẹ́gun wọn. Ó pa gbogbo ọmọ ogun ìlú náà ó sì mú Ìjàkòdọlà ní ẹrú.

Dáhùn ìbéèrè 1 – 10

1. Ìlú ____ jẹ́ ìlú tó ń sàn fún wàrà àti fún oyin.
   A. Ajékìígbé
   B. Àpésìn
   C. Ọ̀tún
   D. Òṣì
2. Orúkọ ọba ìlú Ajékìígbé ni
   A. Ìjàdùọlà
   B. Májẹ̀kódùnmí
   C. Ìyálóde
   D. Àpésìn
3. Ìlú ____ máa ń jowú ìlú Ajékìígbé.
   A. Ọ̀tún
   B. Òṣì
   C. Àpésìn
   D. Ọlọ́yẹ́
4. Orúkọ ọba ìlú Àpésìn ni
   A. Májẹ̀kódùnmí
   B. Ìjàkòdọlà̀
   C. Ìyálóde
   D. Balógun
5. ____ ránṣẹ́ ogun sí ìlú Àpésìn.
   A. Májẹ̀kódùnmí
   B. Ìjàkòdọlà
   C. Ìyálóde
   D. Aṣípa
6. Ọjọ́ mélòó ni ìlú Ìjàdùọlà fún ìlú Ajékìígbé ? Ọjọ́
   A. Mẹ́rin
   B. Márùn-ún
   C. Mẹ́fà
   D. Méje
7. Ọba ìlú Ajékìígbé pe àwọn _____ rẹ̀ sí ìpàdé.
   A. Ọmọ
   B. Ìyàwó
   C. Ìjòyè
   D. Ọ̀rẹ̀
8. Àwọn ìjòyè ìlú Ajékìígbé ni àwọn wọ̀nyí àyàfi
   A. Ààrẹ-Ọ̀nà-Kakanfò
   B. Balógun
   C. Ìyálóde
   D. Ọ̀tún
9. Ta ni ọba àti àwọn ìjòyè rẹ̀ bẹ̀ lọ́wẹ̀ láti gbógun ti ìlú Àpésìn ?
   A. Fábíyìí

B. Ìyálóde
C. Balógun
D. Òṣì

10. Ta ni wọ́n mú lẹ́rú ?
A. Ìjàkòdọlà
B. Òṣì
C. Ọ̀tún
D. Aṣípa

**ESIN IBILE YORUBA**

11. ‘**Olodumare**’ je oruko Olorun ninu ede ______
A. Igbo
B. Hausa
C. Idoma
D. Yoruba

12. Eya wo lo n pe Olorun ni ‘Ubangiji’ ?
A. Efik
B. Urobo
C. Edo
D. Hausa

13. Orisa ile Yoruba ni ______
A. Ogun
B. Gurumaraji
C. Osanobua
D. Chineke

14. Ta ni awon Yoruba n pe ni ‘god of thunder’?
A. Oya
B. Ogun
C. Sango
D. Egungun

15. Which of them usually comes out in the night?
A. Oro
B. Obatala
C. Oya
D. Osun

16. Eledaa tumo si _____
A. The Creator
B. The Almighty
C. The invisible
D. The God of heaven

**TONE MARK IN YORUBA**

17. Ami ohun ede Yoruba je _______
A. Meji
B. Meta
C. Merin
D. Marun-un

18. Iro ohun isale ni ____
A. r r r
B. m m m
C. d d d
D. k k k

19. Ami ohun ti o wa lori ‘iyawo- wife’ ni
A. m m d
B. r r m
C. d d m
D. d m r

20. Ewo ni iro ohun oke ?
A. Mid tone
B. High tone
C. Low tone
D. Side tone

**SILEBU EDE YORUBA**

21. ‘Omolanke’ je oro onisilebu _____
A. Marun-un
B. Merin
C. Meta
D. Meji

22. Konsonanti aranmu asesilebu ni ______
A. N
B. K
C. F
D. G

23. Awon wonyi je oro onisilebu meta **AYAFI** ___
A. Alagba
B. Okuta
C. Omode
D. Alangba

24. Oro onisilebu merin ni _____
A. Olongbo

B. Aja
C. Ewure
D. Akuko

25. Ihun silebu **“alakowe”** ni _____
A. Kf –kf –kf –kf
B. F –kf-kf-kf
C. Kf-kf-f-kf
D. F-f-kf-kf

26. Ewo ninu awon wonyi ni kii se ihun silebu ede yoruba?
A. F
B. Kf
C. N
D. Jk

27. Oro onisilebu kan ni _____
A. Aja
B. Sun
C. Okuta
D. Alaba

**GBOLOHUN EDE YORUBA**

28. Gbolohun abode tumo si ____
A. Simple sentence
B. Compound sentence
C. Complex sentence
D. Interrogative sentence

29. Eyi ti o maa n ni oro-ise méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ ni gbolohun_____
A. Alakanpo
B. Alabpde
C. Olopo oro-ise
D. Gbolohun ibeere

30. ‘Idowu je iresi’, je apeere gbolohun ____
A. Alakanpo
B. Abode
C. Olopo oro-ise
D. Ase

31. Toka si oro-ise ninu, **‘’Alaba je iresi funfun’’**
A. Je
B. Alaba
C. Funfun
D. Iresi

32. Ninu, ‘’**Bode ko ile ti o tobi**’’. Awe gbolohun afarahe ni ____
A. Ti o tobi.
B. Bode ko ile
C. Bode ko ile ti o tobi.
D. Ko ile ti o tobi.

33. Ewo ni gbolohun alákànpọ̀ ?
A. Kunle fe mu omi.
B. Idowu jeun amo ko yo.
C. Sade lo si oja.
D. Sare wa.

34. Gbolohun ase ni awon wonyi **AYAFI** ___
A. Jokoo
B. Dide
C. Olakunle ti sun.
D. Patewo.

35. ‘’**Daily Contribution**’’ tumo si _____
A. Ajo
B. Owe
C. Arokodoko
D. Owo ele

36. ‘’**Bank**’’ ni ede Yoruba ni _____
A. Ile-eko
B. Pensu
C. Iwe
D. Ile-ifowopamo

37. Ewo ni ‘’**Sogun-dogoji**’’?
A. Montly contribution
B. To pay two times of the money you borrow.
C. Credit sales
D. House help

38. Which of these can be used to build a house?
A. Oja awin
B. Aradosu
C. Owe
D. Gbami-o-ra-mi

***SISO IYE AGOGO TO LU***

39. Aago meloo lo lu?



A. Aago meji
B. Aago meta
C. Aago merin
D. Aago marun-un

40. Aago meloo lo lu ni isale yii?



A. Aago kana abo
B. Aago meji aabo
C. Aago meta aabo
D. Aago merin aabo

41. Iye aago ti o lu ni isale yii ni aago __



A. mejila koja iseju mẹ́rin
B. mẹ́rin koja iseju mewaa.
C. eta koja iseju marun-un
D. méje koja iseju mefa.

42. Aago meloo lo lu? Aago _______



A. mejila ku iseju kan
B. kan ku iseju mewaa
C. mefa ku ogun iseju
D. mẹ́jọ àbọ̀

DAYS AND MONTHS OF THE YEAR

43. ‘**Monday**’ ni ede Yoruba ni ojo ___
A. Isegun
B. Aje
C. Abameta
D. Aiku

44. Ewo ni ojo ‘**Abameta**’?
A. Sunday
B. Friday
C. Saturday
D. Tuesday

45. Osu Seere ni ede Geesi ni _____
A. March
B. February
C. January
D. April

46. Ki ni osu December?
A. Belu
B. Ope
C. Owara
D. Igbe

**ONKA YORUBA**

47. 100 ni onka Yoruba ni _____
A. Ogorun-un
B. Igba
C. Ogofa
D. Oodunrun

48. Ki ni ‘**Ọ̀ọ́dúnrún**’ je?
A. 300
B. 400
C. 500
D. 200

49. **#**200 ni ede Yoruba ni ___
A. Igba naira
B. Ogoji naira
C. Aadofa naira
D. Ogorun-un naira

50. Ki ni **irínwó** naira je ni ede Yoruba?
A. N300
B. N400
C. N200
D. N100.

51. ‘**Welcome**’ ni ede Yoruba ni ___
A. E kaabo
B. E kuule
C. O daaro
D. E kaaaro


52. Bawo ni a se n ki onigbeyawo?
   A. E ku inawo iyawo
   B. E ku ewu omo
   C. E ku ojobi
   D. E ku ojo meta
53. 'I am feeling hungary' tumo si ___
   A. Ebi n pa mi
   B. Inu n run mi
   C. Otutu mu mi
   D. Inu mi dun.

**Fi ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó yẹ dí àlàfo nínú ìbéèrè 54 àti 55**

54. Folasade _____ ewa ati iresi.
   A. ge
   B. na
   C. je
   D. pa
55. Alabi n ______ iwe re.
   A. je
   B. ka
   C. din
   D. sun

IDENTIFICATION OF OBJECTS

56. Aworan isale yii ni ___



   A. ẹsẹ̀
   B. ọwọ́
   C. orí
   D. Tabili
57. Ki ni aworan isale yii ni ede Yoruba.



   A. Igi
   B. bàtà
   C. Oko
   D. Aso

**Use the picture bellow to answer questions 58 and 59.**

58. Àwòrán ìsàlẹ̀ ỳí ni ____



   A. ọba
   B. ọlọ́pàá
   C. dókítà
   D. adájọ́
59. Ki ni awon Yoruba n pe eya ara nomba 2?
   A. Enu
   B. Eti
   C. Oju
   D. Orun
60. Ounje isale yii ni ________



   A. àdàlú
   B. dòdò àti ìrẹsì
   C. ègbo
   D. Iyan àti ọbẹ̀ ègúsì

**SECTION B: THEORY (30 MARKS)**

**INSTRUCTION: ANSWER ALL QUESTIONS. ALL QUESTIONS CARRY EQUAL MARKS**

1. Pin awon oro wonyi si silebu. (5 marks)

| Ọ̀rọ̀ | Sílébù |
|---|---|
| Àpẹẹrẹ: | À-pẹ-ẹ-rẹ |
| Ìyàwó | |
| Babáwálé | |
| Aláǹgbá | |
| Àgádágodo | |
| Alárápé | |

2. Daruko ihun silebu awon oro wonyi; (5 marks)

| Ọ̀rọ̀ | Ìhun sílébù |
|---|---|
| À-pẹ-ẹ-rẹ | f-kf-f-kf |
| Ọ̀pẹ̀kẹ́tẹ̀ | |
| Àkàrà | |
| Olóńgbò | |
| Babajíde ́ | |
| Àgbàdo | |

3. Fi ami ohun si ori awon oro wonyi:
   a. d d r – agbado
   b. r m d m – alakowe
   c. d m r m – ipekere
   d. r m d m – alangba
   e. d m r – ibepe (5 marks)
4. Ko oruko marun-un ti awon Yoruba n pe Olorun.(5 names Yoruba call God) (5 marks)
5. Ko awon nomba wonyi ni onka Yoruba.(5 marks)
   a. 100
   b. 200
   c. 300
   d. 50
   e. 20
6. Daruko orisi ounje marun-un ni ede Yoruba. (5 marks)